*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



# Ìdánimọ̀ Tuntun

Ohun tí ènìyàn bá ń ṣe láti ìgbà dé ìgbà yóò di àṣà; àwọn àṣà ènìyàn ló sì ń kó ara pọ̀ di ìwà. Ọ̀pọ̀ ènìyàn ni wọ́n ń ro bí ìgbésí aiyé àwọn yóò ṣe yí padà. Wọn kò fẹ́ ní ìsopọ̀ mọ́ pẹ̀lú àwọn nǹkan ẹ̀gbin àti ìtìjú tí àwọn ènìyàn ti mọ̀ wọ́n mọ́ fún ìgbà pípẹ́. Fún àpẹẹrẹ: Ènìyàn lè máà fẹ́ láti máa bá a lọ ní gbígbé ìgbé-aiyé ọ̀mùtí, ẹni tí ó nlo òògùn olóró, ọ̀pùrọ́, olè, àjẹ́, oṣó, apànìyàn, tàbí ẹni tí ń ṣe panṣágà. O lè jẹ́ irú àwọn ènìyàn yìí. Ohun tí ó dára ni, kí o kábàámọ̀ ohun búburú tí o ti ṣe rí. Àmọ́, ó ṣeé ṣe gan-an ni, kí àwọn ìwà wọ̀nyí tún wáiyé, nítorí pé ìṣẹ̀dá àtijọ́ rẹ ṣì wà. Ìṣẹ̀dá àtijọ́ rẹ yóò wà ní àyíká títí dìgbà tí a bá ti wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù, tí ìwọ́ sì ti ní ìdánimọ̀ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run.



Bíbélì sọ fún wa nípa ọkùnrin kan, tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Jékọ́bù. Jékọ́bù bẹ̀rẹ̀ sí gbé ìgbésí aiyé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí olè àti òpùrọ́. Ó wọ ìwà ká máa tanni jẹ láti gba ohunkóhun tí à ń fẹ́, lẹ́wù; kò sì ní àlàáfíà rárá di ìgbà tí Ọlọ́run fún ní ìdánimọ̀ tuntun (Gẹ́nẹ́sísì 32:27-30). Kódà, ó gba àwọn ìbùkún púpọ̀ tí ó jẹ́ tirẹ̀ lọ́nà òtítọ́, pẹ̀lú ìdánimọ̀ tuntun náà.

Ọlọ́run fẹ́ kí o ní èrò inú tí ó dá ṣáṣá, àti ìwà tí ó dára jùlọ nítorí Ó dá ọ ní àwòrán ara Rẹ̀. Òun yóò fún ọ ní ìdánimọ̀ tuntun, láìka gbogbo ohun búburú tí o ti ṣe. Àmọ́, o gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, kí o sì wá ìbátan pẹ̀lú Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì. Krístì kú lórí igi Àgbélébùú ti Kálfàrì fún ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ẹ̀dá. Ẹ̀jẹ̀ tí Ó ta sílẹ̀



*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



Ìdánimọ̀ Tuntun

Ohun tí ènìyàn bá ń ṣe láti ìgbà dé ìgbà yóò di àṣà; àwọn àṣà ènìyàn ló sì ń kó ara pọ̀ di ìwà. Ọ̀pọ̀ ènìyàn ni wọ́n ń ro bí ìgbésí aiyé àwọn yóò ṣe yí padà. Wọn kò fẹ́ ní ìsopọ̀ mọ́ pẹ̀lú àwọn nǹkan ẹ̀gbin àti ìtìjú tí àwọn ènìyàn ti mọ̀ wọ́n mọ́ fún ìgbà pípẹ́. Fún àpẹẹrẹ: Ènìyàn lè máà fẹ́ láti máa bá a lọ ní gbígbé ìgbé-aiyé ọ̀mùtí, ẹni tí ó nlo òògùn olóró, ọ̀pùrọ́, olè, àjẹ́, oṣó, apànìyàn, tàbí ẹni tí ń ṣe panṣágà. O lè jẹ́ irú àwọn ènìyàn yìí. Ohun tí ó dára ni, kí o kábàámọ̀ ohun búburú tí o ti ṣe rí. Àmọ́, ó ṣeé ṣe gan-an ni, kí àwọn ìwà wọ̀nyí tún wáiyé, nítorí pé ìṣẹ̀dá àtijọ́ rẹ ṣì wà. Ìṣẹ̀dá àtijọ́ rẹ yóò wà ní àyíká títí dìgbà tí a bá ti wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù, tí ìwọ́ sì ti ní ìdánimọ̀ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run.

2

Bíbélì sọ fún wa nípa ọkùnrin kan, tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Jékọ́bù. Jékọ́bù bẹ̀rẹ̀ sí gbé ìgbésí aiyé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí olè àti òpùrọ́. Ó wọ ìwà ká máa tanni jẹ láti gba ohunkóhun tí à ń fẹ́, lẹ́wù; kò sì ní àlàáfíà rárá di ìgbà tí Ọlọ́run fún ní ìdánimọ̀ tuntun (Gẹ́nẹ́sísì 32:27-30). Kódà, ó gba àwọn ìbùkún púpọ̀ tí ó jẹ́ tirẹ̀ lọ́nà òtítọ́, pẹ̀lú ìdánimọ̀ tuntun náà.

Ọlọ́run fẹ́ kí o ní èrò inú tí ó dá ṣáṣá, àti ìwà tí ó dára jùlọ nítorí Ó dá ọ ní àwòrán ara Rẹ̀. Òun yóò fún ọ ní ìdánimọ̀ tuntun, láìka gbogbo ohun búburú tí o ti ṣe. Àmọ́, o gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, kí o sì wá ìbátan pẹ̀lú Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì. Krístì kú lórí igi Àgbélébùú ti Kálfàrì fún ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ẹ̀dá. Ẹ̀jẹ̀ tí Ó ta sílẹ̀

3

lórí àgbélébùú ń wẹ gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀ mọ́; tó túmọ̀ sí pé, Ọlọ́run yóò dárí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì pátápátá ní kété tí o bá ti gbà á gẹ́gẹ́ bí Olúwá àti Olùgbàlà rẹ. Ẹ̀mí Mímọ́ yóò sì wá, láti bẹ̀rẹ̀ sí í gbé nínú rẹ (Éfésù 1:13-14). Lẹ́yìn náà, ìwọ yóò ní ìdánimọ̀ tuntun láti ọdọ Ọlọ́run. Ẹnikẹ́ni tí ó bá ti gba Jésù Krístì ti di ẹ̀dá tuntun. Ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; ohun tuntun ti dé (2 Kọ́ríńtì 5:17).

Níní èrò inú tí ó dá ṣáṣá àti ìwà mímọ́ kìí ṣe nípasẹ̀ agbára ènìyàn - nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ ni. O kò ní agbára láti yẹra fún ẹ̀ṣẹ̀ láìsí Ẹ̀mí Mímọ́.

Kò sí ẹ̀dá alààyè kan tí ó ṣèèṣì wà lórí ilẹ̀-aiyé. Ọlọ́run dá ọ lọ́nà ìyanu fún àwọn nǹkan pàtó láti mú ṣe (Gẹ́nẹ́sísì 1:27-28, Éfésù 2:10).



Gbéra ńlẹ̀, kí o sí tàn! Gba Krístì ní báyìí, láti bẹ̀rẹ̀ síí mú àwọn ohun ribiribi tí Ọlọ́run dá ọ fún, ṣe. Má ṣe dúró ìṣẹ́jú kan!

**Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?**

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.



4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).



**Kí ló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?**

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!



lórí àgbélébùú ń wẹ gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀ mọ́; tó túmọ̀ sí pé, Ọlọ́run yóò dárí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì pátápátá ní kété tí o bá ti gbà á gẹ́gẹ́ bí Olúwá àti Olùgbàlà rẹ. Ẹ̀mí Mímọ́ yóò sì wá, láti bẹ̀rẹ̀ sí í gbé nínú rẹ (Éfésù 1:13-14). Lẹ́yìn náà, ìwọ yóò ní ìdánimọ̀ tuntun láti ọdọ Ọlọ́run. Ẹnikẹ́ni tí ó bá ti gba Jésù Krístì ti di ẹ̀dá tuntun. Ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; ohun tuntun ti dé (2 Kọ́ríńtì 5:17).

Níní èrò inú tí ó dá ṣáṣá àti ìwà mímọ́ kìí ṣe nípasẹ̀ agbára ènìyàn - nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ ni. O kò ní agbára láti yẹra fún ẹ̀ṣẹ̀ láìsí Ẹ̀mí Mímọ́.

Kò sí ẹ̀dá alààyè kan tí ó ṣèèṣì wà lórí ilẹ̀-aiyé. Ọlọ́run dá ọ lọ́nà ìyanu fún àwọn nǹkan pàtó láti mú ṣe (Gẹ́nẹ́sísì 1:27-28, Éfésù 2:10).

4

Gbéra ńlẹ̀, kí o sí tàn! Gba Krístì ní báyìí, láti bẹ̀rẹ̀ síí mú àwọn ohun ribiribi tí Ọlọ́run dá ọ fún, ṣe. Má ṣe dúró ìṣẹ́jú kan!

**Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?**

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.

5

4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

6

**Kí ló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?**

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

7